# IBI MIMỌ́: APẸẸRẸ ISỌDIMIMỌ́

## Ẹksodu 30:1-10; 40:22-28; Lefitiku 4:1-12; 6:30; Heberu 13:11, 12

## ẸKỌ 73 FUN AGBA

**AKỌSORI: "Nitorina Jesu pẹlu, ki o le fi ẹ̀jẹ ara rẹ̀ sọ awọn enia di mimọ́, o jiya lẹhin bode" (Heberu 13:12).**

**I Awọn Ohun Ọṣọ ati Iṣẹ Iranṣẹ ninu Ibi Mimọ́**

1. Pẹpẹ wura fun turari wà ni Ibi Mimọ́, Ẹksodu 30:1-6, 26-29; 37:25-28; 39:33, 36-38; 40:5, 26-28
2. Wọn maa n sun turari ni akoko ẹbọ ẹ̀ṣẹ ati ni akoko adura, Ẹksodu 30:7-9; 40:27; Lefitiku 16:11-13; Luku 1:10; Orin Dafidi 141:2; Ifihan 8:1-4; Malaki 1:11
3. Lori Pẹpẹ wura ni a n fi ẹ̀jẹ ṣe etutu fun ẹ̀ṣẹ abinibi, Ẹksodu 30:10
4. A gbé tabili akara-ifihan kalẹ ni ipo rẹ̀ ni iha ariwa, Ẹksodu 40:4, 22, 23; 37:10-16; 26:35
5. A gbé ọpa fitila meje ti n rú fitila meje si iha gusu, Ẹksodu 40:24, 25; 37:17-24; 26:35

**II Ibi Mimọ́ Apẹẹrẹ Isọdimimọ́ Patapata**

6. A fi ẹbọ ẹ̀ṣẹ ṣe apẹẹrẹ Etutu Ẹjẹ Jesu fun iwẹnumọ ẹ̀ṣẹ abinibi, Lefitiku 4:1-4, 13-15, 22-24, 27-29; Heberu 13:11, 12; Orin Dafidi 51:5-10; Efesu 4:20-24; 5:25-27; Luku 1:74, 75; 2 Kọrinti 7:1; 1 Tẹssalonika 4:3; Johannu 17:9-24; Heberu 2:11; Romu 6:6-12
7. A ṣe etutu fun ẹ̀ṣẹ nipa ibuwọn ẹjẹ, Lefitiku 4:5-7, 16-18, 25, 30; 1 Johannu 1:7; Heberu 9:19-22
8. Ni ẹyin ibudo ni a ti maa n sun ẹran naa, Lefitiku 4:8-12, 19-21, 26, 31, 32; 6:30; Matteu 27:31-33; Heberu 13:11, 12
9. Akara ifihan jẹ apẹẹrẹ ounjẹ ti ẹmi ti i ṣe Ọrọ naa, Lefitiku 24:5-9; Johannu 6:32-58; 1:1, 2
10. Ọpa fitila jẹ apẹẹrẹ Ẹmi Mimọ́ ti n tan imọlẹ si Ọrọ naa, Ẹksodu 25:31-40; 27:20, 21; Numeri 8:1-4; Johannu 1:4, 9; 8:12; 12:46; 2 Kọrinti 4:6; Ifihan 1:4, 13; 4:5

## ALAYE

### Agọ Naa ati Ifarahan Ọlọrun Lori ati Ninu Rẹ̀

A ti ri i pe Agọ nì jẹ ibi ijọsin pataki fun Israẹli, nibi ti Ọlọrun n bá eniyan pade ti eniyan si n sunmọ Ọlọrun. Lati tọ́ awọn eniyan Rẹ̀ sọna nipa ẹsin tootọ, Ọlọrun fun wọn ni oriṣiriṣi apẹẹrẹ ati ami ti wọn le fi oju ri eyi ti yoo fi otitọ iyebiye nipa Etutu fun ẹ̀ṣẹ ati ifẹ Rẹ̀ fun gbogbo araye yé wọn. Pupọ ninu apẹẹrẹ ati àmi wọnyii ni o wà ninu Agọ, ti a kọ́ nipa ọrẹ atinuwa awọn eniyan wọnyii (Ẹksodu 25:2). O wú ni lori lati kà pe awọn ayanfẹ Ọlọrun ni o pese ohun gbogbo fun kikọ́ Agọ naa, ati awọn ohun ọṣọ inu rẹ̀ nipa ọrẹ atinuwa wọn (Ẹksodu 35:21-29).

Awọsanma, ogo Ọlọrun, duro lori Agọ naa lọsan ati loru ni gbogbo irin-ajo wọn ninu aginju. Awọsanma yii, gẹgẹ bi ọwọ̀n ti o n ṣamọna awọn Ọmọ Israẹli ni irin-ajo wọn lati Egipti, fara hàn gẹgẹ bi ikuuku ni ọsan ati bi ọwọ̀n iná ni oru (Numeri 9:15-17). Nigba ti Ọlọrun ba n fẹ ki awọn Ọmọ Israẹli bẹrẹ irin-ajo wọn awọsanma naa yoo ṣi kuro lori Agọ yoo si maa lọ ṣiwaju awọn arinrin-ajo wọnyii, yoo si ṣamọna wọn titi de ibi ti wọn yoo tun duro niwaju. Ọwọn awọsanma jẹ aabo lọsan, ọwọn ina si jẹ amọna wọn ni oru, ṣugbọn "Ṣẹkina" tabi imọlẹ ti o wà ni Ibi Mimọ́ Julọ jẹ "Ifarahan Ọlọrun, nipa eyi ti eniyan fi mọ pe Ọlọrun wà ni tosi." Ọwọn awọsanma ati ọwọn ina jẹ ipese Ọlọrun fun Israẹli, ṣugbọn "Ṣẹkina" ni Ifarahàn Ọlọrun tikara Rẹ̀ ni Ibi Mimọ Julọ, nibi ti olori alufaa nikan ṣoṣo maa n wọ̀ lọ lẹẹkan ṣoṣo lọdun.

### Ọna Sọdọ Ọlọrun

Ẹlẹṣẹ maa n tọ Ọlọrun wa pẹlu ẹbọ irekọja fun awọn irekọja rẹ, eyi ti a pa nibi pẹpẹ idẹ ninu agbala ita niwaju Agọ. Nibẹ ni o ti ni ironupiwada fun awọn ẹṣẹ ti o ti dá; yoo si lo igbagbọ pẹlu; a o si ṣe etutu fun un nipa ibuwọn ẹjẹ. A ko gba awọn eniyan laye lati rekọja ibi yii; bi o ba si n fẹ sun mọ Ọlọrun siwaju si i nipa awọn apẹẹrẹ wọnni ti a le fi oju ri, yoo jẹ nipa ẹbẹ adura awọn alufaa ti i ṣe aṣoju awọn eniyan niwaju Ọlọrun. A o ri pe ọgbọn nla wà ninu eto Ọlọrun yii.

Eniyan maa n fẹ lati fi iṣẹ ọwọ rẹ̀ wá oju rere Ọlọrun, gẹgẹ bi Kaini ti ṣe nigba ti o mu ẹbọ rẹ̀ wá. Ọlọrun n fẹ ki eniyan fi igbagbọ wá sọdọ Rẹ̀ ki a ba le kọ ilana Rẹ̀ si wọn ni ọkàn, ki o ba le ba Ọlọrun rin ni idapọ didùn. Ṣugbọn lati igba de igba ni eniyan n fa sẹyin. Awọn apẹẹrẹ ti a le fi oju ri ṣe pataki; ṣugbọn wọn kò le ṣe etutu fun ẹ̀ṣẹ bẹẹ ni wọn kò si le fun wa ni idariji lọdọ Ọlọrun. Atọka lasan, ati apẹẹrẹ ati aworan ni wọn jẹ fun Ẹbọ nla ti o n bọ̀ wá, ati isin tootọ ti a o fi hàn fun awọn eniyan nigba ti akoko kikún nì ba de nigba ti eniyan yoo sin Ọlọrun lẹmi ati lotitọ, ti ki yoo jẹ ni akoko kan tabi ni ibi kan ṣoṣo (Johannu 4:20-24).

Ọlọrun fi awọn apẹẹrẹ wọnyii fun eniyan lati jẹ amọna rẹ, ṣugbọn ọgbọ́n Ọlọrun fi aalà si ayè ti lilo wọn de. Bi o ba ṣe pe a gba olukuluku olujọsin láyè lati wá si Ibi Mimọ lati ṣe ibuwọn ẹjẹ ẹbọ ẹṣẹ rẹ niwaju aṣọ ikele ati lati fi ninu rẹ sara awọn iwo pẹpẹ wura nibi ti turari mimọ ti n jo nigba gbogbo, kò ni pẹ lọ titi ti gbogbo isin naa yoo di alaini laari. I ba ti di iṣẹ-isin ode ara lasan; igbagbọ tootọ, pẹlu ẹmi isin tootọ ati ironupiwada, i ba ti sọnu. Kì ba ti si iyatọ laaarin ẹsin Israẹli ati ti awọn Keferi ilẹ Kenaani ti a fi awọn Ọmọ Israẹli rọpo wọn.

**Ibi Mimọ́**

Nigba ti eniyan ba mu ẹbọ irekọja wa, fun idariji awọn ẹṣẹ ti o dá nipa yiyan ati idanu ara rẹ, irugbin ẹṣẹ wa ninu ọkan rẹ sibẹ, ẹṣẹ abinibi ti a ni lati wẹnu kuro. Eyi ni iṣẹ ti a ṣe ninu ọkàn nipa iriri ti a n pe ni Isọdimimọ Patapata. Gẹgẹ bẹẹ, apẹẹrẹ fun iriri iyanu ti oore-ọfẹ yii ni Ọlọrun ṣe fun Israẹli ni Ibi Mimọ́ ninu Agọ. Ọkọọkan ninu awọn ohun ti o wà ninu yara yii ni o n tọka si apakan tabi omiran ninu eto Ọlọrun fun nini iriri ologo yii. Kiki awọn alufaa ni o maa n wọ Ibi Mimọ́, wọn a si wọ ibẹ gẹgẹ bi aṣoju awọn eniyan. Ẹni ti o mu ẹbọ ẹṣẹ naa wa yoo duro lode ninu adura gbigba. Niwọn bi o ti jẹ pe Ọlọrun ni o fun ni ni iriri naa, a le ri i pe eyi ki i ṣe nipa ilàkàkà ti rẹ tabi iṣẹ ọwọ rẹ; bi ko ṣe nipa adura rẹ si Ọlọrun pẹlu igbagbọ. Lọna bayii ni ọgbọ́n Ọlọrun gba fi idi isin tootọ mulẹ ni aye.

Niha ariwa Ibi Mimọ́ naa ni tabili kan wa ti a fi igi ṣittimu ṣe ti a si fi wura bò. Lori tabili yii ni a fi akara ifihan mejila si ti a to ni mẹfa-mẹfa ni ila kọọkan pẹlu turari lori ila kọọkan. Awọn alufaa nikan ni o n jẹ akara yii, awọn ti a yà si mimọ́, wọn a si maa jẹ ẹ ni Ibi Mimọ́. Eyi jẹ apẹẹrẹ ounjẹ ẹmi ti Ọrọ Ọlọrun eyi ti o maa n jẹ́ ti wa nigba ti a ba ni iriri ologo yii.

Ni iha gusu tabi ni apa osi bi alufaa ti n wọle ni a gbe ọpa fitila ti a fi wura ṣe si. Eyi ni o n tan imọlẹ si iyara ti i ba ṣokunkun. Aṣọ isorọ ti iwaju ati aṣọ mẹrẹẹrin ti a fi bo o kò le jẹ ki imọlẹ miiran wọ inu iyara naa. Eyi jẹ apẹẹrẹ Ẹmi Mimọ́ ti n tan imọlẹ si Ọrọ Ọlọrun ti a gbin sinu ọkàn ti a sọ di mimọ́ ni tootọ (Ifihan 1:4; 4:5).

**Pẹpẹ Wura**

Laaarin meji, niwaju aṣọ ikele nla ti o pin Ibi Mimọ́ niya pẹlu Ibi Mimọ́ Julọ, ni pẹpẹ wura ti turari wà. A ki i ṣe ẹbọ sisun lori pẹpẹ yii. Ohun ti a n lo o fun pataki ju lọ ni sisun turari ti a yà si mimọ́. Ẹṣẹ nla ni lati fi turari ajeji tabi ina ajeji rubọ lori rẹ, tabi fun ẹnikẹni lati wa ṣe iṣẹ-isin nibẹ nipa awọn alufaa, tabi ki ẹnikẹni ṣe turari mimọ́ yii tabi ki o lo o ni ọna miiran. Nitori ẹṣẹ keji ti a darukọ loke yii ni Nadabu ati Abihu fi kú (Lefitiku 10:1, 2); nitori ẹkẹta ninu awọn ẹṣẹ wọnyii ni ọba Ussiah ṣe di adẹtẹ (2 Kronika 26:16-21); ijiya iku ni a pinnu ti a si mu ṣẹ lori awọn eniyan fun ẹṣẹ kẹrin (Numeri 16:35-40).

Sisun turari lori pẹpẹ wura jẹ apẹẹrẹ adura awọn eniyan mimọ́ (Orin Dafidi 141:2; Malaki 1:11; Ifihan 8:3, 4) awọn eniyan a si maa gbadura lode nigba ti alufaa ba n fín turari (Luku 1:10). Òórùn didùn ti o n lọ soke nigba gbogbo yii n ṣe apẹẹrẹ idapọ aidẹ́kun (1 Tẹssalonika 5:16-18) ti o jinlẹ ju ti atẹyinwa nigba ti a ba sọ ọkàn di mimọ́ ti a mu ẹ̀ṣẹ abinibi kuro; ti aworan Ọlọrun – ododo ati iwa mimọ́ tootọ -- bọ sipo (Efesu 4:24; Kolosse 3:10). Ọkàn ti a sọ di mimọ́ patapata ni o le ni iru odiwọn mimọ́ bayii.

**Ẹbọ Ẹṣẹ**

Ṣugbọn ki a ba le mu ẹṣẹ abinibi kuro a ni lati ta ẹjẹ silẹ (Heberu 9:22); eyi ni Ọlọrun si ṣe ilana rẹ ninu irubọ ti a mọ ni ẹbọ ẹṣẹ laaarin awọn Ọmọ Israẹli. A maa n pa ẹran ti a fi rubọ fun ẹbọ irekọja lori pẹpẹ idẹ. Nipa ẹbọ yii ni a n ṣe ilaja pẹlu Ọlọrun, lẹyin ilaja yii ni eniyan le mu ẹbọ ẹṣẹ wa fun wiwẹ ẹṣẹ abinibi nù patapata kuro ninu ọkàn rẹ. O ṣe pataki pe ki iyipada wà ninu eto irubọ yii nitori bi a ba n ṣe irubọ iru kan naa ni ibi mejeeji yoo mu ki idaru dapọ wà ti yoo mu ki o ṣoro lati mọ ohun ti ẹbọ wọnyii n ṣe apẹẹrẹ rẹ̀.

Nibi pẹpẹ idẹ ni a ti n pa ẹbọ ẹṣẹ. Lẹyin naa a o mu ẹjẹ rẹ̀ lọ si Ibi Mimọ́ a o si fi wọ́n iwaju aṣọ ikele lẹẹmeje, a o si fi ẹjẹ naa sara iwo pẹpẹ wura. Nigba ti a ba ti ṣe eyi, a ti ṣe etutu fun ẹṣẹ, bayii ni ẹni naa tabi iye awọn ti o mu ẹbọ yii wá yoo ri iwẹnumọ gbà. A o si sun ara ẹran ti a pa yii lẹyin ibudo. Jesu, Ẹni ti I ṣe Ẹbọ pipe, ni o mu gbogbo apẹẹrẹ etutu wọnyii ṣẹ. A sọ fun wa ninu Iwe Heberu pe, nigba ti a ba sun ara awọn ẹran wọnni lẹyin ibudo, ẹjẹ eyi ti a mu wa si Ibi Mimọ́, eyi n ṣe apẹẹrẹ iku Kristi lẹyin bode Jerusalẹmu fun isọdimimọ́ wa (Heberu 13:11, 12).

A jẹ ajigbese gidigidi si Kristi nitori ẹbọ etutu ti O ṣe, nitori ni Kalfari ni o pese igbala kikun fun wa. Ohun ti a n pe ni igbala kikun ni gbogbo iriri Onigbagbọ ti a ri gbà bẹrẹ lati igba ti Ọlọrun mu idalẹbi ẹṣẹ wọ inu ọkan wa, ti O si mu wa wá sọdọ Kristi, titi di igba ti a gbà wá soke lati pade Rẹ̀ ni awọsanma. Ẹni ti o dá Ijọ Igbagbọ́ Apọsteli silẹ maa n sọ nigba pupọ pe isọdimimọ́ patapata jẹ "koko pataki ju lọ" ninu iriri Onigbagbọ, nitori lai si iwa mimọ́ ko si ẹni ti yoo ri Oluwa (Heberu 12:14).

Satani ti gbe afarawe gbogbo iriri Onigbagbọ kalẹ nipa ṣiṣe ayederu wọn, ṣugbọn nigba ti ko ṣe e ṣe fun un lati fi ohunkohun dipo iwa-mimọ́, o tun ti wá awọn ọna arekereke miiran gbogbo nipa iriri ti o ṣe iyebiye yii. O mu ki awọn miiran sẹ́ ẹ, o mu ki awọn miiran fi oju tinrin rẹ, o si dori ẹkọ Bibeli nipa iriri yii kọ odò fun awọn miiran. Ṣugbọn a dupẹ lọwọ Ọlọrun pe otitọ Rẹ̀ ṣi wà ninu ayé sibẹ ati pe awọn ti wọn n lakaka lati ni gbogbo ẹ̀kún ibukun

Ọlọrun le ni iriri nla keji yii, lai si eyi ti ko ṣe e ṣe lati wọ Ibi Mimọ́ Julọ -- eyi ti i ṣe apẹẹrẹ iriri nla-nla ti ifiwọni Ẹmi Mimọ́ ati iná.

**AWỌN IBEERE**

1. Ṣe apejuwe bi Ibi Mimọ́ ti tobi to.
2. Orukọ miiran wo ni a tun fi n pe Ibi Mimọ́, ninu iwe Heberu?
3. Ki ni n tan imọlẹ si Ibi Mimọ́? Apẹẹrẹ ki ni imọlẹ yii jẹ́?
4. Igba meloo ni a n paarọ akara ifihan? Apẹẹrẹ ki ni o jẹ́?
5. Ki ni a n fi rubọ lori pẹpẹ wura? Apẹẹrẹ ki ni eyi jẹ́?
6. Nigba ti a ba fi ẹjẹ ẹbọ ẹṣẹ wọn iwaju aṣọ ikele ti a si fi i sara iwo pẹpẹ wura, apẹẹrẹ ki ni eyi jẹ́?
7. Ki ni n ṣẹlẹ si ara ẹran ti a fi ẹjẹ rẹ sara pẹpẹ wura? Ka ẹsẹ Majẹmu Titun ti o n tọka si apẹẹrẹ yii.
8. Ta ni n wọ Ibi Mimọ́? Ki ni ohun ti wọn ni lati ṣe lati ni ẹtọ lati wọ Ibi Mimọ́?
9. Sọ iyatọ ti o wa laaarin eto ẹbọ fun idariji ẹ̀ṣẹ, ati ẹbọ ẹ̀ṣẹ fun iwẹnumọ ọkàn.
10. Ki ni ṣe ti Satani ko le ṣe ayederu isọdimimọ́ gẹgẹ bi o ti ṣe ti idalare ati ifiwọni Ẹmi Mimọ́ ati iná?